IROHIN IMỌLẸ

IMỌLẸ ỌRẸ A/YE TẸNI GBOGBO LAWA

No, 757 THURSDAY JULY 30. 1964 (2D)

## Okpara Youths Brigade Tọrọ Aye Lati Lọ Ri Awolọwọ

IBADAN:- Ẹka ẹgbẹ Okpara Youths Brigade ni Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria tọrọ aye lọwọ Alakoso ọgba ẹwọn ilẹ Naijiria lati lọ ṣe ibẹwo olori ẹgbẹ Afẹnifẹre to wa ni ọgba ẹwọn ni ilu Kalaba ni Ipinlẹ Ila Orun Naijiria

Awọn ọmọ ẹgbẹ Okpara Youth Brigade tun rọ Alakoso ọgba ẹwọn ilẹ Naijiria lati le fun awọn enia ti ko ju meji ninu awọn ọmọ ẹgbẹ wọn ni Ipinlẹ Iwọ Orun Naijira lati lọ ṣe ibẹwo Oloye Awolọwọ ni ọgba ẹwọn Kalaba

Gẹgẹbi irohin ti a ri gbọ ninu ọsẹ to kọja ni a ti gbọ pe gbogbo awọn ọrẹ ati awọn ọmọ ẹgbẹ Olori ẹgbẹ Afẹnifẹre na to nfẹ ṣe ibẹwo Oloye Awolowọ lọsẹ to koja pe awọn to jẹ Alakoso ọgba ẹwọn ni Kalaba ko fun wọn laye rara.

Ninu iwe ti awọn ọmọ ẹgbẹ na kọ lati ọwọ akọwe agba ẹgbẹ na Ọgbẹni Okunọla Ọlawuyi fi ye pe ni o jẹ okan to tọ ati eyi to yẹ lati le ṣe abẹwo Oloye Awolọwọ.

Awọn ọmọ ẹgbẹ na tun sọ pe gẹgẹbi Alakoso Akọkọ ni Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria, awọn ọmọ ẹgbẹ na sọ pe ni akoko Oloye Awolọwọ ni Ipinlẹ na pe eto alafia wa ati pe lati igbati o ti fi Ipinlẹ Iwọ Orun silẹ ni ko ti si eto alafia ati Ijọba rere,

# AWỌN ỌBA NṢE ETO LORI OWO—OṢU ỌBA AKARIGBO

IBADAN:— Ko si ni buru ki o ma ku ẹnikan mọ ni, eyi lo mu ki awọn Ọba kan ni Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria gbero lati pari ija to wa larin Ọba Moses Awolesi Akarigbo ti ilu Ijẹbu-Rẹmọ ati Igbimọ Afunishọ ti Ijọba ibilẹ ti ilu Rẹmọ lori owo-oṣu Ọba na ti Ijọba Ibilẹ na sọ di kọbọ kan ṣoṣo ni ọdun.



Oloye S. L. Akintọla

Awọn Ọba to jẹ ẹlẹgbẹ Ọba na ti nwọn fẹ ṣe eto lati pari ija na ni Ọba Gbadebọ, Alake ti ilu Abẹokuta ati Ọba Ọlateru Ọlagbegi keji Ọlọwọ ti ilu Ọwọ. Ninu ọrọ awọn Ọba na fun awọn oniwe irohin ni ọjọ Aiku ti iṣe ọjọ kejidinlogun Osu yi ni Gbọngan ti Ijọba ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria awọn Ọba na sọ pe nwọn yio sọ eto ipari ija na di ọjọ kẹrin Oṣu ti nbọ yi.

Igbimọ afunishọ ibilẹ ilu Rẹmọ ṣe adehun nibi ipade pajawiri kan ti awọn igbimọ na ati Alaga igbimọ Ọba Green Adebọ Ọba Olushan ti ilu Ilishan ṣe laipẹ yi ni awọn igbimọ na sọ pe nwọ yio ge owo Oṣu Ọba Awolesi ku si kọbọ kan ṣoṣo l'ọdun fun ẹsun ti igbimọ afunishọ ti ijọba ibilẹ ilu Rẹmọ fi kan Ọba na pe o nlọwọ ninu eto oṣelu ati pe awọn kan fi afin Ọba naṣe ile ipade wọn

Ninu awọn enia to wa nibi ipade lati pari ija larin Ọba Akarigbo, Ọba Moses Awolesi ati Igbimọ afunishọ ti Ijọba Ibilẹ ilu Rẹmọ na ni Ọmọba Adeleke Adedoyin Alaga ile Igbimọ asofin Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria, Ọba Akarigbo ti ilu Ijẹbu-Rẹmọ, ati awọn Ọba meji ti nwọn fẹ



Ọdẹmọ ti ilu Ishara
Ọba S. Akinsanya



Ọba Awolesi
Ọba Akarigbo Ijẹbu Rẹmo

ṣe eto lati pari ija na Ọba Ọlagbegi keji Ọlọwọ ti ilu Ọwọ

Gẹgẹbi irohin lati ọwọ oniwe irohin wa fi ye wa pe ohun ti o mu ki awọn Ọba na sọ akoko ti nwọn yio pari ọrọ na di ọjọ kẹrin oṣu ti mbọ yi ni pe Alaga Igbimọ afunishọ ti Ijọba ibilẹ ilu Rẹmọ, Olishan Ọba ti ilu Ibishan ko wa si ibi ipade lati pari ọrọ na nitori pe Ọba Adebọ Green Olishan ilu Ilishan ni ẹjọ kan lati lọ jẹ ni ile ẹjọ giga ti Ijẹbu Ode ni ọjọ na.

Oniwe irohin wa tun fi ye wa pe ọmoba Adeleke Adedoyin ati Ọba Moses Awolesi Akarigbo ilu Rẹmọ fun awọn igbimọ ti yio ṣe eto lati pari, ọrọ na ni ọrọ diẹ nipa ohun to fa ti awọn igbimọ afunishọ ti Ijọba ibilẹ ti Ijebu- Rẹmọ ge owo oṣu Ọba na di kọbọ kan ṣoṣo l'ọdun.

Awọn igbimọ ti nse eto lati pari ija awọn igbimọ afunishọ ti Ijọba ibilẹ ilu Rẹmọ ati Ọba Akarigbo ti Ijẹbu-Rẹmọ tan ṣe ipinnu lati pari ija to wa larin awọ Ọba nwọnyi pẹlu awọn igbbimọ afunishọ ti awọn ijọba ibilẹ ti ilu Itaji, oye ati Ikarẹ awọn Ọba ti Ijọba ibilẹ na tun ge owo oṣu wọn di kọbọ kan ṣoṣo

l'Ọdun ni Ọba Onitaji ti ilu Itaji Ọba Oloye ti ilu Oye ati Ọba Olukarẹ ti ilu Ikarẹ ṣugbọn awọn Ọba ti nṣe eto lati pari

Ija na ko si sọ ọrọ kan lati le fi mọ gẹgebi ọrọ na ti lọ si. Nigbati Ọba Gbadebọ, Alake ti ilu Abẹokuta jade kuro ninu Gbọgan ti Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria ni Ọba na fi ye awọn oniwe Irohin pe awọn ti ti ṣe eto kankan lori Ija ti awọn fẹ pari na.

Ọba Gbadebọ tun sọ pe awọu san asiko ti nwọn yio ṣe eto lati pari ija na di ọjọ kerin oṣu ti nbọ yi nipe lati le ri aye pe awọn igbimọ afunishọ ti Ijọba ibile na lati le wa sẹ alaye ti ẹnu wọn fun ohun to mu nwọn gbe owo oṣu Ọba na di kọbọ kanṣoṣo lodun



Adeleke Adedoyin

Ọba Ọlatẹru Ọlagbẹgi keji Ọlọwọ ti ilu ọwọ fi ye awọn oniwe Irohin lehin ti nwọn jade kuro nibi ipade na pe ko ti si Ọba kankan to jẹ pe iru nkan bẹ si ẹlẹ si lati ri pe nwọn ge owo oṣu awọn ku si kọbọ kan ṣoṣo l'ọdun ri ati eyiti o le mu ki awọn Ọba dahun si ni ipinlẹ yi ri.

# AYUNỌRUNBỌ ATI PANPALASO (Apa Kini)

Ki nto tun bẹrẹ itan mi Oloyin mọmọ yi, nko le ṣai ki ẹyin Onkawe Irohin Imọlẹ ati Olotu iṣẹ iwe na pẹlu awọn alabaṣiṣẹ rẹ, Oluwa ninu anu rẹ, Oluwa ninu anu rẹ ki o lọra ẹmi gbogbo nyin o, ẹko ni ṣe e ti ni ile aiye yin o lagbara Baba loke-Aṣẹ Lai ṣe aniani ọpọlọpọ nyin ni o ti nka awọn Itan mi bi Ajiran ilu Oku ati Igbo *Eṣu* beleke ninu iwe Irohin Yoruba o si jẹ ifẹ inu mi lati tun ma fi itan aladun yi bẹ ẹnyin onkawe Irohin Imọlẹ ẹ ma ka iwe imọlẹ dada lojumọ ki ẹ le ma gbadun Itan mi.

## Lati Ọwọ J, O. SHOYINKA

Lẹkansi nko le ṣai ṣe adura yi ṣaju nitoripe ọmọ Oduduwa abidi pọnripọn abidi pọn, yariya abidi ya Ọpe a uju abidi yaramuyaramu On lọ difa fun Olugan Ọmọ Araba b'ẹgbẹrin Ọmọ, Olu Ọgan wa d'ọlọwọ loni o yaya ẹ ka sai dolowo, yaya Olu ogan wa dọlọmọ loni o, yaya ẹka ṣai dọlọmọ yaya Akarugudu lorukọ ti a npe ifa Osunbẹlẹjẹ lorukọ ti a npe Iwọ orun o fi koko rugudu pọnmi Ọtaratara lorukọ ti anpe iwọ Ogburu gburu Ori Oku Njẹ Oṣo ile lọ ba npori mi nibi Igbetantan, lera nke wọle igbe. Njẹ bojẹ aje ile lo ba npori mi nibi Ehin oku la njẹ akara ilu fọ ẹhin wọn ni ngo ma jẹkara wọn gbogbo ẹnyin Oluka itan mi Ọmọ araiye ko ni foju si. nyin lara sibẹ sibe bi oti wu ki Ọmọ de ji to iwaju ni yio ba kukute.

Ni kukuru mo juba awọn Oṣewe patapata mo juba awọn Baba to bi mi lọmọ. iba Yẹru Okin Olalomi Ọmọ abisu jorukọ ijakadi loro Offa, Ọrun rere o, baba atata-Iba Eṣu lalu okiri oko onișokoto penpe ti Sonibode Ọlọrun, o bẹlẹkun sunkun kẹru o ba ẹlẹkun, ẹlẹkun nsunkun laroye nsun ẹjẹ.

Iba ilẹ ohun ajẹgba enia ma wukọ, iba awọn Iya mi Oṣorongan, afinju ẹiyẹ ti njẹ ni ile ika arumọloogun danu, omi gbigbona ti ko ṣe bu mu, mo juba ki iba mi temi ṣẹ. Itan mi bẹrẹ lori Ayọnrunbọ ati Panpalaṣo

Nigba lailai ilu kan wa ni ilẹ *Yoruba* ti a npe ni "Ori eru" awọn olugbe ibẹ jẹ alalupayida, nwọn ko ni abọ, iṣẹ idan pipa ati adahunșe ni nwọn nșe, kiki ajẹ si ni obinrin ibẹ Eyi jẹ ki ilu ajẹ si lokiki to bẹ gẹgẹ ti o fi jepe ẹniti o ba fẹ gba ajẹ tabi o fẹ ṣe oṣo ibẹ ni nwọn lọ. Epinni ni nwọn fi nșe oṣo. kọbọ ni wọn si fi ngba ẹiyẹ Ajẹ nibẹ. Ilu yi jẹ ilu kereje, o da do sori oke tente, li owurọ kutukutu a ma yọ efin tuu Gẹgẹbi ẹnyin papa ti mọ pe ilu ki wa koma ni Ọba ati awọn akọni enia, Orukọ ọba ti mo nsọ itan rẹ yi - ma jẹ GBANGBALAṢANTA, awọn akọnl meji kan si wa nibẹ. Awọn ara ilu na bi nwọn tijẹ abam enia to yi, ni ibẹru wọn li kan nitoripe nwọn buru jọ alujannu lọ. Orukọ ekinni njẹ Ponpalaṣo, orukọ eni njẹ Ayunọrunbọ, awọn keji jeji yi si jẹ Opidan, nwọn nleri ara wọn ti pẹ, wọn ti ọjọ kan awọn yio jọpe, li ode idan pipa lati pade ọkunrin. Nwọn ti n le ri labẹlẹ ọjọ ti pe, ileri yi kan ọba, o pe wọn bati ro rẹ o ni on gbọ esi iyẹwu panpalaso li o kọkaibaibai, pe bẹni, Ayunọrunbọ dahun sọ pe otitọ ni Ọba da si ọjọ meje pe ki nwọn padẹ ni agbole on lati wa pitu inu wọn awọn mejiji gba bẹẹ nwọn pada lọ si ile, olukuluku bẹrẹ si lọdi ara wọn lorișa,

Li owurọ Ọjọ keji, ọba paṣẹ pe ki alagogo ilu lu agogo yika ilu pe ni ọjọ mẹfa oni, Gbugburu yio ta ni agbode on nitoripe Panpalaṣo ati Ayọrunbọ yio fi Ọkunrin han ara wọn, Gbogbo awọn ara ilu ni o wire o wire o, awọn mejeji si ba ara wọn sọ pe gbugburu ikan kọ ni yio ta ẹpa papa yio ta pẹlu,

### APEJUWE AYỌRUNBỌ

Ko ni kun to, ko si ni dun to, ti nko ba sọ iru enia ti Ayunọrunbọ je-Ayunọrunbọ ga to ẹsẹ mẹfa Ọkunrin to Ọkunrin, irin rẹ dabi ẹnipe agbanrọ—ti o ba nrin lọ ilẹ ama mi titi-ti, iṣan ara rẹ ri waro-waro, odabi itakun inu igbo, ẹniti o ba sun mọ, yo ma gbọ bi ẹjẹ ara rẹ ri nșan ya-ya-ya bi agbara, okuku rẹ dabi ọmọ ori Odo, ko si genge Ọlọrun to le gba ọkan duro, igẹ rẹ ri fẹrẹfẹrẹ bi iwe ipẹlọ oju rẹ dẹruba ọmọde ni kukuru iri ri rẹ fi han pe akọni enia ni ise

Nigbati o gbọ ohun ti o ti wi tan, ko ya ile rẹ lọ nse ni o kọkọ gba ọdọ awọn iya mi osoronga hiohio lọ oko gbogbo rẹ oro fun wọn. Nwọn ni ki o ma lọ si ile, ati pe ọwọ ọmọde ki ka igi ọṣẹ, yio ma doyika ni.

O dupẹ lọwọ nwọn o si rekọja si ọdọ ẹgbẹji ologun o ba nibi ti o ti nyana,o ki o yilẹ, Ẹgbẹji ni sa mi dide Oluwa mi, Ọkunrin kọgibọti, o ni kin o de o? Ayọọrunbọ ko oro fun o si bere pe njẹ oha ti ya ọdọ awọn iya mi oṣorogạ hiohio? afinju ẹiyẹ ti njẹ ni ile Ika, Omi gbigbo na ti ko ṣe bu mu bi? oni on ti ya.

Ẹgbẹji ti lere ohun ti wọn ni, nwọn sọ pe ki on ma lọ, ọwọ ọmọde ki ka igi ose Ẹgbeji rẹrin ha!ha!! oni nisisiyi ni ọkan mi to wa balẹ lati fun ọ ni ọfọ ati ogun ti o daju nitoripe ologun ti ko ba fi ti ajẹ ṣe, omulẹ mofo ni gbogbo ogun ti o ṣe yio jasi.

O fun ni agadagodo amu ni muye o kọ ni lilo rẹ awa fun ni apo kan ti ẹwọn tiorio wa ni ninu rẹ, o fun ni ilo rẹ kanna Ayọnrunbọ paapa wa ti ni agbo kan ti baba rẹ tida fun ojojumọ lo nwẹẹ, nitori aitamọ Panpalaṣọ lefẹ ju ni atare Imurayi pọ to bẹ gẹẹ ti o fi wipe ko si orun fun titi alẹ ọjọ kẹfa, igbayi ni orun ejika to kun osi sun lọ fọn fọn ẹnikan kan ilẹkun gbagba o taji o sure dide warawara o si silẹkun piri yiyọju ti yio yọju si ita ni o ri obinrin kan, ogun ori gbalaja Obirin yi kii, oni ọdọ rẹ ni mo wa.

iyoku di ọla

The NEW HOOVER
Washing Machine
Makes Clothes
Whiter and Brighter
It's easier the ...
HOOVER way



The NEW HOOVEMATIC washes rinses spins dry 6lbs. of clothes in 4 minutes all in one continuous operation. That's the amazing performance of the new Hoovermatic, a combined Washing Machine and Spin Dryer.

AVAILABLE AT
LEVENTIS TECHNICAL
MARINA — IDDO — IBADAN—
KADUNA — JOS — KANO—
P. HARCOURT — ABA.
and Kingsway Stores.

# IWE SI OLOTU

## Irohin Imọlẹ D'araba Loni

Mo dupẹ nihin, lọwọ Oluwa Ọga Ogo to ṣọwa di ọjọ oni, nitorikini bi enia ba se ni lore ọpẹ ladu ki a le ri omiran gba, ani to mu wa wa laiye, laye, ni alafia ti mo tu nba iwe Irohin Imọlẹ yọ ti ajọdun ọdun kẹsan ti o bẹrẹsi jade, ti o si tun pe ọdun kan gbako ti o di iwe irohin ojojumọ nitori iwo yi eṣi ni a ba iwe na yọ ti iwe irohin ojojumọ ti o di,

Inu mi dun pupo mo si lo aye yi ni oruko awon onkawe Irohin Imolẹ ni Dahomey lati fi ki Olotu iwe na ati gbogbo awon oṣiṣẹ iwe na ku ewu orire Oluwa yio tun bo ma ran yin lowo ọwọ awon Alakoso iwe Irohin Imole yio ma roke o, Eni elẹni ko ni gba iṣe won ṣe o E ko ni ṣi tẹ o

Lagbara Oluwa ni asiko ti ẹ bẹrẹ odun titun miran yi iyi pada nla yio tun wa ninu iṣẹ yin o A bo mi re o mo ki yin ku orireo.

Emi ni,

Ọgbẹni L. N. Adeshiyan Onilu faji Aṣoju iwe Irohin Imolẹ Ni Dahomey.

## Mo Kan Sara Si Olotu

Bi ọmọ eni ba dara o yẹ ki a wi, ani oyẹ ki a sọ ki isẹ bi kẹ a fi se aya Olotu Irohin-imọlẹ Ọgbẹni Tunji Adeọsun dara l'ọmọkurin, ise nlanla ti ko se fi enu rohin ni o se fun igbega Irohin Imọlẹ



TUNJI ADEOSUN

Olotu Irohin Imọlẹ

Mo ki Olotu na ati gbogbo ẹyin onkawe Irohin Imọlẹ ku ayọ ẹ ku orire ti iwe Irohin na ti o pe odun kan ti a bẹrẹsiri Iwe na ka ni ojojumọ mo dupẹ lọwọ Eledumare ti o san awọn Alakoso iwe na lọwọ ti o fi njade lojumọ.

Isẹ nla ti ko se fi enu sọ ti awa enia Naijiria ko ni gbagbe ni iwe Irohin Imole na se nfun gbogbo awa ọmọ Yoruba o fun wa ni irohin kikun nipa awọn nkan ti o nsẹ kakiri agbaiye l'ojojumọ Iwe na si duro gedegbe ni, laifi aramọ ẹgbẹ oselu kankan ti ko si bikita lati ma tẹ ẹdun ọkan awa ara ilu jade fun Ijọba laise oju saju

Ni idi eyi mo lo akoko mi yi lati fi ki Alakoso, olotu Osiṣẹ ati gbogbo ẹyin onkawe Irohin Imọlẹ ku orire Oluwa yio ma ran gbogbo wa lọwọ o iwaju lopa ẹbiti nresi iwaju ni ẹ o ma lọ

Emi ni

Fahdatu Arẹago

Eko

## Mo Ba Iwe Irohin Imọlẹ Yọ

Pẹlu idunu ati ayọ ni mo fi lo anfani ti mo ni lati fi ki Alakoso ati Olotu, Irohin-Imọlẹ ku ewu ti ajọdun ọdun kan ti iwe na bẹrẹsi jade l'ojojumọ.

Ki ato bẹrẹ aroye nipa iṣẹ ti iwe na ti ṣe ṣehin fun ogo orilẹede Yoruba, mo ni lati kọkọ dupẹ lọwọ Olọrun Ọba Oludari awa ẹda alaye, ti o ndari iwe na si ọna rere, ti ko si jeki iwe na lugbadi ofin Ijọba, ti ko jẹki o d a k u, A dupẹ l ọ w ọ Allah ti o se amọna iwe na, ti o si ndari Olotu si ọna rere Ti ko si sọ iwe na si ero ẹhin lati ibẹrẹ rẹ. Ọpẹ ni fun Oluwa.

Iṣẹ nla ni iwe na ti ṣe sehin, ti a ba ni ki a ma sọ iwe a kun, a ko tilẹ le sọ tan, melo ni a o ka ninu ẹhin adepele. Olotu A dupẹ lọwọ rẹ. Oluwa yio tun bọ maṣe amọna rẹ Ọpọ ti o fi ṣe eto iwe na ko ni daru Iwaju ni o ma lọ,

Lakoian mo si dupẹ lọwọ ẹnyin oṣiṣẹ iwe na fun ọna ti ẹ gba ti a fi tete ri iwe na ta nihin lojojumọ. Iru ẹ la o ma ri o,

Emi ni,

Lateef Animasahun

Asoju Irohin Imọlẹ

IBADAN

## Naijira kan Ni A Nfẹ

N sisiyi o ṣe nlo si ẹdun kerin ti a gba ominira bi a ba sun ri osu kan si loni yio di ọdun kan ti a gba Repobiliki sugbọn lati gbana nkọ? kini a ri osi isọkan larin wa, o to akoko fun awọn olori wa lati jiroro lori eleyi, Naijiria kan ni a nfẹ ẹ masẹ jẹki a pin ara wa wẹlẹwẹl.

Nitorina ẹnyin agbagba ẹ ba wa ṣe eto yi ẹ fi Awolọwọ silẹ ati gbogbo awọn ẹlwọn oṣelu orilẹede yi nitori ọkan ninu awọn ti o ja fun Ominira wa ni Oloye Awolọwọ nṣe. Laisi Awo ko le si alafia ati isọkan ni ilu, ẹ ba wa tete ṣe eto yi ki al fia irẹpo isokan ati ki eto aje orilẹ-ede yi le ma lo deede Ko si owo lode o.

Naijiria kan ni a nfẹ o.

Emi ni

Latifu Babalola

EKO



Oloye AWOLỌWỌ


# MODUPE PRINTING PRESS

LEADERS IN MODERN PRINTING

*Firms Patroise* MODUPE PRES *Because Of Their:—*

MODERATE CHARGES
EFFICIENCY
GOOD PRINTING
IMPERISHABLE RECORD
DELIGENT SERVICES
ACCELERATIVE METHOD PRINTING

*For Your Next Printing Jobs:—*

Just Call 21985 - Leave the rest to Modupe

We Granantee Neat Work And Quick Service

**Modupẹ Printing Press**

**16 Bgbosee Stre**

Phone. 21985, Lagos

...NGBA DẸKUN! KEDERE BẸWO!!




Bi amodi "IKỌ" ti ọjọ rẹ ti pẹ tabi ti o nyọ ẹ lenu on akan bi ọdun kan tabi jubẹ lo awọn egbogi rọ irọbi fun le se iwosan rẹ rara, ma fi owo rẹ se owo ofo mọ.

Bere fun egbogi awọn ara. Ilu Faranse ti wọn npe ni PORAL ojulowo hanunhanun, a amatase egbogi fun I otutu, Ikọ ọna ọfun, Ikọ Igbaaya, Ikọ iil. Ikọ ti o mọ mu enia tu kẹ ẹbẹ nigbakugba lati inu "Ifun wa (Lungsa tabi ti o ba nmu enia ru pẹlu.

Bi o ba lo an Igo kan PORAL yi wa Iwọ na yio ri iya to ninu ara re ni kiakia Igbaaya tabi ọna ọfun re ti o ma nho yio duro "IKỌ" rẹ yio si san ni patapata iwọ yio ma jẹun daradara iwọ yio si un fọnfọn pelu alafia de

Bere egbogi yi ni awọn orisiri i L8b gi Ikọ miran ni Ṣọbu awọn:—

NIGERIAN MEDICINE STORES
4 Tinubu Square, Lagos

WATERLOO MEDICINE STORES
8, Palmchurch Street, Lagos

Phone:- 2287 Nigeria, (Ojalta Faji) ......
Adedun Chemist
14, Weakman Street, Yaba

# Onitausiri Olododo ni Hadija Abudu Raha man Makanju

Lati ọwọ Hadji Y. A. Disu

Bi ọmọ ẹni ba dara, ẹ jẹki a sọpe, o dara ki iṣe de aye ati ifẹ lati fi i ṣe aya Hadji A. R. Makanju jẹ ọkan pataki pataki ni ojulowo Mọṣalasi Jimọh Eko lariwo gbogbo awọn Arikewuyọ ati awọn Onitausiri yika ilu Eko. ki iṣe kẹnimani enia ki iṣe dongo opurọ ki iṣe do ogo onisọkusọ

O mọ kewu ke da ada ohun rẹ dara pupọ- oni faaa

Pataki ninu awọn ẹbun rẹ ti Ọlọrun fun un ni pe, o ni igboiya lati sọ ọrọ ati tọ, o si mọ ọrọ sọ pupọ. Ẹnu rẹ dun bi oyin, O si ni ifaiyabalẹ si Ọlọrun.

Ni Jimọh, Jimọh ti o ba ṣe tausiri ni ojulowo Mọṣalaṣi Jimọh Eko n awọn janmọ (ijọ) ma a ngbadun rẹ Irufẹ ẹru Ọlọrun bayi ni a nfẹ ki o ma

a ṣe tausiri (waasi fun wa ni gbogboigba. Ki Ọlọrun fi kun mimọ rẹ, ki o tubọ fi ibukun si mimọ rẹ, ki o si fun un ni ẹmi gigun pẹlu alafia.

A ko fẹ ẹniti ko gbedegbẹyọ ti ko si ni ẹmi ododo lati ma a ṣe waasi yika ilu Eko, Olododo ki i ku si ipo ika Olododo ati enia Ọlọrun ti fẹ ki a maa ṣa

# Yẹ Irawọ Rẹ Wo

AQUARIUS (Jan. 21-Feb. 19) Gbogbo awọn eto ti o ti se silẹ nibi iṣẹ rẹ gbogbo nfẹ ẹ daru, m a ṣ e jafara lati yi awọn eto na pada, ki o si ṣe eto omiran

PISCES (Feb. 20-March 20) Maṣe jafara lati din irin a o rẹ tabi gbokegbodo rẹ ku, ki o s i k a p a ojukokoro rẹ tabi, ki o mu oju kuro ninu awọn nkan ti o e mu ọ na owe.

ARIES (March 21-April 20) Ki o ma ko ẹ g b ẹ kiri, tabi ki o ma ba awọn ẹgbẹ lọ si ode faaji kakiri jẹ eyiti yio ṣe ọ ni anfani.

TAURUS (April 21-March 22) Gbogbo a w ọ n nkan ti o ba dawọle ni ṣiṣẹ lọjọ ti oni, ire ati adun ni igbehin rẹ yio jasi, Ere nla kan si mbọ fun ọ ni jijẹ

GENINI (May 23 - Jun 21) Inu rẹ yio dun jọjọ fun irohin rẹ ti Ọkunrin gbajumọ kan yio sọ nipasẹ nitoripe Ọkunrin na ni ifẹ didun si ọ.

CANCER (June 22 - July 22) Ṣe inawo sibi ti enia yio ma rohin rẹ iwọ yio si gbọ irohin ti yio ṣe ọ ni anfani lẹle ọna daradara ti o ti ngba ṣiṣẹ tẹlẹ ri.

LEO (July 23 - Aug 22) Pipẹ ti opẹ ni owurọ yi nipa ọrọ ile yio kẹki nkan jọlọ ki o to to akoko ọsan, yio dara fun gbogbo ohun ti o nleba ati faari larin ẹgbẹ fun ire ati igbadun.

VIRGO (Aug 23 - Sept 22) Poro iru iwa ti o tinhu larin awọn ẹbirẹ nitoripe gbogbo ọgbọn ori rẹ pẹlu suru ni iwọ ni lilo rẹ nigbati akoko rẹ ba de.

LIBRA (Sept 23-Oct23) Ohun ti yio tun yọju si ọ n sisiyi ni wipe iwọ yio rin irin ajo kan lairo tẹlẹ o dara ki oni awọn ọrẹ titun

SEORPION (Oct24 Nov22) Awọn ẹbi rẹ ati ọrẹ rẹ yio fe idunu ati ayọ wa ba ọ isami rẹ dara bi o ba mba awọn ọmọde sire.

SACITTARIUS (Nov23 Dec21) Ipade iwọ pleu olori buruku kan yio da rogbodiyan kan silẹ fun ọ l san eni ṣugbọn die ninu imọran rẹ yio ṣe anfani fun

CAPRICORN (Dec22 Jan20) Gbogbo iṣẹ rẹ loni yio ẹ ire ati anfani fun ilọsiwaju rẹ ni iṣẹ rẹ


GBOGBO ARA ILU NKỌ ORIN IYIN ati AYỌ NIPA "DYNAMIREN" TỌNIKI



ALE-BI-ELE Egbogi Tọniki Jamọnu titun ti gbogbo ... Ilu Eko ati jakejado Naijiria mọ daju fun Akọ gbara ati Ajẹbidan iṣẹ Rẹ lara Agbalagba Ọkunrin gbogbo

Bi arẹ ara ba nmu ọ, nigbakugba fun wahala lala ṣiṣẹṣẹ ti o kọ ie jẹun daradara, tabi ki o male sun dada ọkun lọsan tabi loru tabi awọn iṣan ara rẹ gbogbo ki ṣe fun daradara ti Eemi (Breath) inu ko ba gunlẹ daradara wọn iṣẹ tabi wahala ṣiṣe tabi fun awọn ailera gbogbo 'nyin ti ọjọ ori rẹ (age) ba ti kọja Ọgbọn ọdun o si de adọrin tabi jubẹ lọ. Mo dupẹ "DYNAMIREN' ni egbogi ti e nfẹ lati sọ ara di ọtun patapata anu rẹ a si jọlọ, ẹran ara rẹ ti o ti hunjọ yio bi ẹ s'i do dada. Ara rẹ yio ma gbe kankan nigbakugba y'Arẹ" n gbakugba yio salọ pẹlu igbadun ati alafi diro de ọ. Iyẹn daju. Bere Egbogi na ni Ṣọbu: awọn

NIGERIAN- MEDICINE STORE
4, Tinubu Square Lagos

Waterloo Medicine Stores
8, Palm church Street, Lagos.
hone: 22878 Nigeria, (Ọja Ita Faji)

ATI NI AWỌN ṢỌBU
OLODUMARE DISPENSARY
IṢẸ IBADAN



# Ẹkun Rẹrẹ Idajọ Oloye Awolọwọ (Apa 12)

NI ỌJỌ TI ILE ẸJỌ ŞE ıDAJỌ

Ki adajọ ile ẹjọ kekere to da ẹjọ ẹwọn ọdun mewa fun Oloye Awolọwọ ni ọjọ kọkanla oşu kẹsa ọdun 1963 ni adajọ ile ẹjọ na Ọgbẹni Şowẹmimọ sọ pe Oloye Awolọwọ ko fẹran A'akoso Ijọba apapọ ati Alakoso Ijọba ipinlẹ Ariwa ati pe iwa ikansinu si Oloye Awolọwọ ni si awọn enia si jinlẹ pupọ.

AWỌN ỌRỌ TADAJỌSỌ

Adajọ ile ẹjọ kekere tun fẹnu kan eto ẹgbẹ igbimọ Amoye ti ẹgbẹ Afẹnifẹre da silẹ adajọ na tun sọ ninu idajọ rẹ pe on gba ẹri ti Dọkita Ọnabamiro jẹ ati ti pa ọrọ rẹ lori igbimọ Amọye ti ẹgbẹ Afẹnifẹre

Adajọ ile ẹjọ tun fiye ile ẹjọ pe eleyi pẹlu ohun ti oloye Awolọwọ ti ko fi fẹran-Alakoso mejeji atipe ohun mu da igbimọ silẹ lati leri aye silẹ lati le tun da rogbodiyan silẹ

Ọgbẹni Sowẹmimọ sọpe Dọkitọ Ọnabamiro lẹ eleri otitọ eyiti ojade lati wa jẹri ri ninu ẹjọ to lewu pupọ bayi

Adajọ ile ẹjọ na tun sọ pe on mọ pe Dọkita Ọnabamiro kole purọ mọ oloye Awolọwọ rara ati pe on mọ pe yio jẹ enia igbẹhin ti yio jẹri irọ bẹ mọ Ijọbu ẹgbẹ rẹ

Adajọ tun se akajuwe ẹjọ na gẹgẹ bi ẹjọ ọrọ oselu ati pe on mọ iru nkan to tun wa ninu ọrọ eto oselu ati awọn ohun isoro ti ile ẹjọ dojukọ ninu ẹjọ na

Onidajọ Sowẹmimọ tun f'ẹnu kan awọn ọrọ ti Agbẹjọ rọ fun awọn Odaran sọ eyiti nwọn pa ẹsun iditẹ mọ ti igbogun ti Ijọ-



Oloye Awolọwọ

ba apapọ ninu ẹsun na eyiti o sọ pe "ko si ohun to tọ a lati mu awọn ẹsun na. O tun fi imọ ọran rẹ han Adajọ na tun sọ pe ko si ohun to tọna ninu awọn nkan ti agbẹjọro ro so oyiti ole jẹ ohun ti a le gba gbọ ninu ẹsun na.

Adajọ na tun sọrọ lori eto Oşelu ni ilẹ Naijiria ati pe awọn ẹgbẹ Oşelu si tan ni igbagbọ ninu imọ wọn Adajọ ile ẹjọ na pọ pe ti a ba tun ro igbesi aiye Oloye Awolọwọ ninu eto Oşelu ati pe enia lati ro ohun tọ mu da igbimọ Amoye silẹ eyiti o jẹ wipe fun imọ lati gba Ijọba apapọ ilẹ Naijiria.

Adajọ ile ẹjọ na tun fi ye ile ẹjọ pe o yẹ ki nwọn mọ gẹgẹbi imọ na ti şe jakulẹ si Adajọ tun sọ pe fun ọmọ wọn lati da igbimọ Amoye silẹ o ni nwọn tun ni imọ lati ran awọn enia lọ si Ghana lati lo fun ẹkọşẹ işẹ ogun Oni sugbọn



micheal Omisade

awọn agbẹjọro si ka ọrọ na si ọna miran. Adajọ tun sọ pe awọn agbẹjọro tun sọ pe awọn ẹgbẹ N, P, C, lo nfẹ pa ẹgbẹ Afẹnifẹre re,

KINI ŞE TO JẸ AŞIRI

Ogbẹni Sowẹmimọ sọ ninu idajọ rẹ pe ti a ba yọ awọn kan kuro ninu awọn ẹleri fun ile ẹjọ awọn enia bi Dokita Maja, ogbẹni Arthur Grand ti o jẹ Alakoso ile ẹkọ ati awọn Ọlọpa awọn enia bi Ibrahim Imam ti o jẹ ọkan ninu awọn Ọmọ ẹgbẹ Afẹnifẹre ti ti di oni laijẹ pe nwọn yọ kuro l'ẹgbẹ Adajọ na tun fẹnu kan idasilẹ Igbimọ Amoye ẹgbẹ Afẹnifẹre o tun bere pe kini şe ti igbimọ na le wa ni aşiri ati pe kini o le fa si aşiri ẹgbẹ igbimo Amoye na le se ni agbara lo bẹ?

Adajọ na sọ pe on gba gbọ pe Dokita pe Ọnabamiro lẹ okan ninu awọn igbimọ na ati pe awọn igbimọ na ni Oloye Awolọwọ Sam Ikoku ati Oloye Anthony Enahoro.

Adajọ na tun f'ẹnu kan ẹri Dokita Ọnabamiro nipa ero ti igbimọ Amoye ro lati gba Ijọba apapọ nibi ipade ti awọn igbimọ na şe ati ero wọn lati ran awọn enia lọ si Ghana lati lọ kọ işẹ ogun ati ero wọn lati le gba Ijọba apapo Naijiria lai jẹ pe lori eto bi ko şe lati da rogbodiyan silẹ.

Ọgbẹni Şowẹmimọ tun sọ pe on gba Dokita Maja ati Ọnabamiro nipa ọmọ lori gẹgẹbi nwọn yio şe gba apapọ Ijọba ati pe awọn enia na ko fi igba kan mọ ara wọn ri. Adajọ na tun ke abaimọ lori eto oşelu ni ile Naijiria eyiti o fi sọ pe nwọn ko si fẹran ara wọn Adajọ tun se apejuwe rẹ gẹgẹ bi ohun ti ko dara rara. Adajọ na tun bu ẹnu ẹtẹ lu eto oşelu ilẹ Naijiria ninu ede lo le pe awọn Oşelu na ko si fẹran awọn ati pe nwọn si lẹnu fun iwa buburu

Nigbati adajọ tun mu ẹnu kan awọn ẹlẹri fun Oloye Awolọwọ meji Dokita S A Aluko ati ọjọgbọn Victor Oyenuga eyiti eyiti o fi sọ pe awọn enia le sa ni pa irọ lori nkan ti ti nwọn kọ sinu iwe iranti

Adajọ na tun fẹnu kan ẹri ti nwọn jẹ nipa ti Jakande eyiti awọn ẹlẹri fun ile ẹjọ sọ pe Lateef Jakande lo san owo fun awọn to nlọ fun ẹkọ işẹ ogun

Adajọ ile ẹjọ na tun fẹnu kan awọn iwe ti Oloye Enahoro kọ si Oloye Awolọwọ ni bi ti o ẹnu kan ọrọ nipa awọn akọwe ati pe adajọ si bere iru awọn akọwe wo ni awọn enia na? Adajọ na tun sọ pe kini o le mu ti Enahoro le mu bere lọwọ Oloye Awolọwọ pe kini şe ti nwọn sanwo fun awọn akọwe na? Adajọ tun sọ pe ti ọrọ awọn ẹleri na jẹ otitọ kini şe ti nwọn fi sọ pe Oloye Awolọwọ

Adajọ sọ pe on mọ pe awọn akọwe na jẹ otitọ ati pe nwọn si lọ kọ wọn fun eto işe akowe ati pe ẹkọ ti nwọn lo fun si jẹmọ eto ẹkọ nipa bi nwọn yio şe na lo ohun Oşẹ.

Adajọ ilẹ ẹjọ na sọ pe on mọ gbangba pe eto igbimọ Amoye ti ẹgbẹ Afẹnifẹre si jẹ mọ eto lati fi agbara gba Ijọba apapọ Naijiria Adajọ tun sọ pe on ri mọ pe ẹri ti Oboh ati Oleari jẹ si iṣẹ malẹ ati pe Ohun to fi jẹ pe o fẹ mọ lẹ wipe nipa eto ẹkọ iṣẹ Ogun ti nwọn lọ fun ni Ghana Adajọ tun sọ pe on ri mọ pe o yẹ ki enia le gbe gbogbo ọrọ na yẹ wo patapata ni nkan to wa ninu ọrọ na.

Adajọ ilẹ ẹjọ na tun sọ pe o gba gbọ nipa ipade ti awọn Ọdaran wa se ni ile Ayọ Akinsanya O tun sọ pe nipa abẹni si ile iṣẹ Electincle ati nkan ti nwọn sọ pe Oloye Awolọwọ sọ fun Oleari nipa ilẹ işe na to sọ pe ki o ba jẹ at awọn nkan to le ba jẹ ni ile iṣẹ Electiriki ni Ijọra ti yio fi ba gbogbo ti ile Naijiria jẹ.

Ọgbẹni Sowemimọ sọ ninu idajọ rẹ pe ohun to dun on pupọ ju ni ọkan ninu awọn enia to jiya fun Ominira ilẹ Naijiria ni Oloye Awolọwọ jẹ ati pe fun enia to jẹ pe o ti jẹ Alakaso ipinlẹ kan ri ti o tun jẹ olori Alatako ni ile igbimọ asofin ati apapọ, Ijọba ti o tun jẹ Ọgbọkan ninu awọn asofin ile Naijiria loni ati pe o si dun o pupọ pe Oloye Awolọwọ to tun ra rẹ pilẹ sẹ ile lo un fe wo o lulẹ ati papa oe o si jẹ oba to şoro fun un lati şe.

IROHIN IMOLE

IMOLẸ ORẸ AIYE, TENI GBOGBO LAWA

No. 757, THURSDAY, JULY 30, 1964 (2D)

## Eni Mẹta Ku Ninu Jamba Mọto

AJEGBO awọn Abiyamọ to rkọja ni oju ọna Eko si Ibadann ati awọn enia to wa ni abule kan ti njẹ Ajẹgbo ni oju ọna Eko si Ibadan lo bu sẹkun nigbati nwọn ri ẹjẹ ọmọ enia to nsan bi omi odo ni ọjọ Aje ti iṣe ọjọ kẹtadinlọgbọn oṣu yi mọto meji kọlu ara wọn ti enia mẹta ku lẹsẹkẹsẹ ti jamba Mọto na ṣẹlẹ ni ọjọ na

Jam'a M ọ t o yi ṣẹlẹ ni irọlẹ ọjọ na nigbati awọn Moto akero meji yi kọlu ara wọn lojiji nigbati nwọn fun ara loju ọna eyiti o gba ẹmi enia mẹta patapata.

Gẹgẹbi irohin lati ẹnu awọn ọ l ọ p a ti o lọ sibi ti J a m b a Mọto na ti ṣẹlẹ fi ye oniwe Irohin wa pe awọn to ku lẹsẹkẹsẹ ni Alhaji Tairu Burama Maiduguri ati Tijani

Ọpọlọpọ enia lo si fara pa ninu jamba Mọto na ṣugbọn lẹsẹkẹsẹ ni nwọn ti ko awọn enia na lọ si ile iwosan ti Adeọyọ ni Ibadan fun itọju

Awọn ọlọpa si ti mu awọn Direba meji to wa Mọto na lati lọ s ohun fa jamba Mọto na bayi.

# AWỌN AKẸKỌ ẸGBẸ AFẸNIFẸRE FẸ ṢE IPADE

IBADAN:— Awọn Akẹkọ ẹgbẹ Afẹnifẹre jake jado ile Naijiria ati orilẹ ede miran ti nmura silẹ fun eto ipade kan ti awọn ọmọ ẹgbẹ na yio ṣe ni ọjọ Eti ti iṣe ọjọ kẹkanlelọgbọn oṣu yi ni ile iṣẹ awọn ẹgbẹ na ni Oke-Ado Ibadan.



OLOYE ỌBAFẸMI AWOLỌWỌ
Olori Ẹgbẹ Afẹnifẹre

Gẹgẹbi irohin to de ọwọ wa lati ọwọ akọwe ipade na Ọgbẹni C A Ajepe ti ye wa pe gbogbo awọn ile ẹko giga julọ ti ilẹ Naijiria (Universities) ni yio ni awọn aṣoju wọn nibi ipade na Ọgbẹni Ajepe tun fi ye oniwe irohin wa pe awọn to jẹ Alakoso ninu ẹgbẹ Afẹnifẹre bi igba enia ni yio wa sibi ipade na ati enia adọta le ni irinwo ti nwọn yio jẹ awọn to wa lati wa gbọ ohun ti nwọn yio sọ ni nu ipade na.

Awọn ọpọlọpọ ẹgbẹ miran ni yio wa sibi ipade na ninu awọn ẹgbẹ ti yio wa lati wa gbọ ohun ti nwọn yio sọ nibi ipade na ni ẹgbẹ ọdọ Afẹnifẹre ni orilẹ ede Naijiria ati awọn ọmọ ẹgbẹ Afẹnifẹre lati ilu Oyinbo ati ilu Ghana ni yio wa sibi idade na.

Irohin tun fi ye wa pe awọn ọmọ ẹgbẹ Akẹkọ ti ẹgbẹ Alakoso (N C N C) ẹgbẹ awọn ọdọ ti a npe ni Naijiria Y o u t h Congress ati ẹgbẹ kan to tun njẹ The Socialist Workers and Farmers Part gbogbo awọn ẹgbẹ nwọnyi ni awọn ẹgbẹ Akẹkọ ti ẹgbẹ Afẹnifẹre pe sibi ipade na.

Ninu awọn nkan ta gbogbo ti awọn ẹgbẹ Akẹkọ ti ẹgbẹ Afẹnifẹre na fẹ ṣoro le lori pupọ ni ẹ bẹ kan t i awọn ọmọ ẹgbẹ A k ẹ kọ Afẹnifẹre fẹ da s i l ẹ eyiti n w ọ n pe n i 'Awolọwo Freedom Committee." Awọn ọmọ ẹgbẹ Akẹkọ ti ẹg ẹ Afẹnifẹre tun s ọ pe ẹgbẹ na ko si faramọ ẹgbẹ oṣelu rara ati pe enia to ba ni ifẹ pe ki eto Ijọba rere ati ilọsiwaju wa f u n ilẹ Naijiria ati pe ti nwọn ba nfẹ ki nwọn fi Oloye Awolọwọ silẹ lati ọgba ẹ w ọ n ati lati le jẹ ki ọ g b ọ n ti Ọlọrun fun Oloye Awolọwọ lati le jẹ ki o ti tun ile Naijiria se

Ninu awọn enia pataki ti yio wa sibi ipade ọ j ọ na ni Alhaji D. S. Adegbenro, Oloye, Iya afin H I. D. Awolọwọ Alhaji Busari Obisẹsan, Oloye J. Ọdẹbiyi ati Ọjọgbọn V. Oyenuga eniti yio ba a w ọ n ipade n a sọrọ ati ọpọlọpọ awọn enia jankan—jankan miran ni yio wa sibi ipade ọjọ na.

Ninu awọn nkan miran ti awọn ọmọ ẹgbẹ Akẹkọ Afẹnifẹre na yio tun f'ẹnu kan nipa gẹgẹbi awọn yio se da ẹgbẹ kan silẹ eyiti nwọn o ma pe ni "Student Front" ti yio jẹ eka kan ninu ẹgbẹ Afẹnifẹre Awọn ọmọ Akẹkọ ẹgbẹ na yio tun fẹnu kan nipa eto ajumọsepọ ẹgbẹ Afẹnifẹre ati ẹgbẹ Alakukọ ati awọn ẹgbẹ oṣẹlu miran ni orilẹ ede Naijiria awọn ọmọ ẹgbẹ na yio tun fẹnu kan eto nipa atunse ẹgbẹ Afẹnifẹre ati nipa imura silẹ fun didibo to ubọ yi

Ọgbẹni Ajepe akẹkọ kan ni ile ẹkọ Unifasiti ti Ibadan fi ye oniwe irohin wa pe awọn ọmọ ẹgbẹ na yio mura nipa eto bi awọn ọlọpa yio ṣe ma se itọju gbogbo asiko ipade n i t o r i awọn ẹhanna ẹgbẹ oselu miran ki nwọn ma le da ija silẹ.

Ninu irohin kan lati ọwọ awọn ọmọ ẹgbẹ Okpara Youths Brigade ni Ibadan awọn ọmọ ẹgbẹ ni sọ pe eto ofin ati Ijọba rere ti bẹ sile ni ipinlẹ Iwọ orun Naijiria ati pe ohun ti yẹ nisisiyi nipe ki nwọn tu ile igbimọ asofin ipinlẹ Iwọ Orun ka l ti le tete ṣe idibo titun si ile Igbimọ na.

Awọn ọmọ ẹgbẹ kan ti nwọn tun npe ni Ondo Provincial Youth Front tun kesi Ọgbẹni D K, Olumọfin Alakoso eto ẹkọ fun Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria pe ki o yẹ ara rẹ wo nipa owo oṣu Ọba Amusa Momọh kẹta Olukaiẹ ti ilu Ikarẹ eyiti Igbimọ Afunishọ ti Ijọba ilu Ikarẹ sọ pe nwọn yio da owo oṣu re duro fun odindi oṣu mẹfa gbako, Awọn ọmọ ẹgbẹ na sọ pe gbogbo nkan ti awọn Igbimọ Afunishọ na nṣe pe ọwọ awọn Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria eyiti ẹgbẹ Dẹmọ N N D P nṣe Alakoso rẹ lo ti jade Awọn ọmọ ẹgbẹ na tun sọ fun Ọgbẹni D K Olumọfin pe ki o tun ile rẹ ṣe ki o to ma kesi Arẹ ilẹ Naijiria.

Printed and Published by Modupẹ Printing Press 16, Bamgbose Street Lagos Phone 21985
Editor: TUNJI ADEỌSUN 45, Campbell Street Lagos 30/7/64.